# Agbéjáde Ìpinnu Beijing Ati Atẹ Akitiyan Ìmúṣẹ́ṣe Nibi



ÌPÀDÉ ÀGBÁYÉ ELEKERIN LÓRÍ Ọ̀RỌ̀
ÀWỌN OBÌNRIN TÓ WÁYÉ NI
BEIJING, CHINA, LỌ́DÚN 1995

# ÌPÀDÉ GBOGBOGBÒ BEIJING

Produced by
The United Nations Development Fund for Women (UNIFEM)
And the United Nations Information Centre, Nigeria (UNIC)

## A TRANSLATION OF THE BEIJING DECLARATION AND THE PLATFORM FOR ACTION IN YORUBA

*By*
**BÁYỌ̀ TÌJÁNÍ**

# ÌPÀDÉ GBOGBOGBÒ BEIJING ỌGBỌ̀NJỌ́ OṢÙ KẸJỌ-ỌJỌ KẸẸ̀ẸDÓGÚN OṢU KẸSÀN-ÁN ỌDÚN 1995 ÌTUMỌ̀ WO LÓ NI SI ÀWỌN OBINRIN NI NÀÌJÍRÍÀ

Ipade gbogbogbò ti Beijing jẹ́ ọkan lára ọlọ́kan-ọ̀-jọ́kan ìpàdé gbogbogbò tí Ajọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé (UNITED NATIONS) gbe kalẹ̀ ninu eyi ti ọrọ obinrin ti jẹ́ lájorí ọrọ. Ó wáyé lati ọgbọ̀ńjọ́ oṣu kẹjọ di ọjọ kẹ̀ẹ̀ẹ́dógún oṣu kẹsàn-án, ọ̀pọ̀ lo si gbà pe òun ni ó lérò jù tí ó sì yọrí si rere ju gbogbo àwọn ìpàdé gbogbogbò lórí ọ̀rọ̀ obìnrin ní àsìkò tí a wà yìí. Ó lé ní ẹgbẹẹgbẹ̀rún lọ̀nà mẹ́rìn-dín-láàdọ́ta obìnrin tí ó ṣe aṣojú àwọn obìnrin gbogbo láti bíi orílẹ̀-èdè mẹ́tà-lé-lọ́gọ́sàn-án ó lé díẹ̀ nibi ìpàdé náà. Wọ́n kó ìfà ètò ìṣèlú Beijing láti gbé ohùn wọn sókè kí wọn sì jọ fẹnu kò lórí awọ̀n ohun to ṣe kókó tí àwọn obìnrin lágbàáyé fẹ, kí àtúntò lè bá ètò ìṣèlú àti ọrọ̀ ajé lórílẹ̀ èdè káàkiri kí àwùjọ wa lè tò, wọ́n tún mẹ́nu ba kókó méjìlá pàtàkì tí ó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ obìnrin. Àwọn wònyí ni ètò ìlera obìnrin, ìwà ìpánle sí àwọn obìnrin, ẹkọ́ fún àwọn obìnrin, bí ó ṣe jẹ́ òtítọ́ pé ìdá ààdọrin nínú ọgọ́rùn-ún àwọn obìnrin ni ìṣẹ́ mù daru, ẹ̀tọ́ obìnrin gẹ́gẹ́ bí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, pàtàkì ipa wọn nínú ètò ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú, ifún lágbára, àjọpín agbára àti ìpinu ṣiṣe fún àwọn obìnrin, ipa burúkú ti ògun àti aáwọ̀ ń ní lórí àwọn obìnrin àti ìṣòro gbogbo tó ń kojú ọmọbìnrin. Àwọn obìnrin bèèrè fún ìbáṣepọ̀ tuntun láàrin ìjọba àti àwùjọ kí wọn lè jọ ṣiṣẹ́ pọ̀ láti kojú àwọn ìṣòro pẹ́pẹ̀pẹ́ gbogbo. Wọ́n fẹ́ ń ọ̀nà ìdàgbà sókè tuntun, ìgbèrú ọrọ̀ ajé tí ó máa kojú àwọn nǹkan tí ó tí ń dí àwọn obìnrin lọ́wọ́ láti kopa àti láti jèrè pẹlu àwọn ọkùnrin láti ara àwọn ètò àti ìyọrí sí ìdàgbàsókè. Wọ́n fẹ ń àrídájú pé ohun èèlò àti ètò wà fún ìjábọ̀ láti mú àlá wọn ṣẹ kí wọ́n si fi ìbéèrè àwọn obìnrin sínú ètò àyè tuntun. Wọ́n fẹ́ kí obìnrin ní ipò kan náà pẹ̀lú àwọn ọkùnrin nínú ẹbí àti àwùjọ fún ànfàání àwọn ọmọ: ọkùnrin àti obìnrin.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó lé ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta obìnrin tí ó ṣojú fún Nàìjáríà ní Beijing, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni o tún kópa pàtàkì nínú ìpalẹ̀mọ́ àti ìṣètò fún ìpàdé náà. Ó ṣe pàtàkì láti fi àwọn ìpinnu tí wọ́n ṣe lórí ọ̀rọ̀ gbogbo obìnrin, tó àwọn ènìyàn púpọ̀ létí fún àǹfààní ogunlọ́gọ̀ àwọn obìnrin àti ọkùnrin tí wọn kò ni aṣojú níbẹ̀.

Láti jẹ́ kí ètò pàtàkì yìí ṣeé ṣe, méjì nínú àwọn aṣojú Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé ni Nàìjíríà-Àjọ Ìṣọkan tó ń ṣétò ìkówójọ fún ìdàgbàsókè ọ̀bìnrin (UNIFEM) àti àwọn Elétí ọfẹ fún Àjọ - Ìṣọ̀kan (UNIC) para pọ̀ láti ṣe àkojọ ìpinnu náà, kí wọ́n túmọ̀ rẹ̀ sí èdè mẹ́ta pàtàkì tí à ń sọ ní ilẹ̀ Nàìjíríà, kí wọ́n sí pín in fún ọ̀kẹ́ àìmọye àwon obìnrin àti ọkùnrin ilẹ̀ Nàìjíríà. Eléyìí ni wọ́n lérò pé ó máa sọ fún ará ìlú, ohun tí wọ́n pinnu àti àwọn nǹkan tí a lè ṣe láti fun àwọn obìnrin ní àgbéga. Wọ́n tún lérò pé èyí máa jẹ́ kí àmúṣe lè bá àwọn ìpinnu náà, tí àwọn afẹ́nifẹ́re lóbìnrin, lọ́kùnrin, ìjọba, oníṣé àdáni, kí ìgbé ayé tuntun níbi tí dééde tí máa wà láàrin ọkùnrin sóbìnrin, kí ìdàgbàsókè tó dúró dééde àti ìbàlẹ̀ ọkàn lè wà ní sẹ́ńtíúrì tó ń bọ̀. Èyí ni ogún pàtàkì tí a lè fi lé àwọn ògo wẹẹrẹ tó ń bọ̀ lẹ́yìn lọ́wọ́.

By: **Prof. Felicia Ekejiuba,**
*UNIFEM Regional Adviser.*

## ÌPINNU BEIJING

1. Àwa ìjọba tí ó kópa nínú ìpàdé gbogbogbò kẹ́rin lórí obìnrin.

2. Kóra jọ ní Beijing ní oṣù kẹ̀sàn-án, ọdún 1995, ọdún tí Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé ń ṣe ayẹyẹ àádọ́ta ọdún tí wọ́n dá a sílẹ̀.

3. Pinnu láti ṣíṣé lórí ìṣedéédé, ìdàgbàsókè àti ìbàlẹ̀ - ọkàn fún gbogbo obìnrin káàkiri, fún àǹfààní gbogbo omonìyàn.

4. Jẹ́rìí sí gbígbọ́ ohun gbogbo obìnrin káàkiri pẹ̀lú ṣíṣe àkíyèsí ọ̀nà ìyapa wọn, ipa àti ààyè wọn. Ṣe nǹkan ìwúrí fún àwọn obìnrin tó ṣínà pẹ̀lú ìwúrí nípa ìrètí tí ó wà lára àwọn ọ̀dọ́ àgbáyé ìwòyí.

5. Ri mọ̀ pé àyè obìnrin ti gbèrú ní àwọn ipò kan ní bí ọdún mẹ́wàá sẹ́yìn ṣùgbọ́n ìdàgbàsókè náà kò gún, àìṣe déédé láàrin obìnrin àti ọkùnrin sì wà síbẹ̀; ọ̀pọ̀ ìdíwọ́ ló ń súyọ, èyítí àpadà sí ẹ̀, lè burú jáì nínú ìgbé ayé àwọn ènìyàn.

6. Tún ri mọ̀ pe irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ń le sí i nítorí ìṣẹ́ tó ń pọ sí i nínú ìgbé ayé ọpọ èèyàn lagbaaye, paapaa julo laarin awon obinrin ati awon omode, eyi ti o n jeyo, kaakiri opo orile-ede ati lágbàyé.

7. Fi ara wa jìn pátápátá láti dojú kọ àwọn ìṣoro wọ̀nyí kí ìdàgbàsókè àti ìgba agbára lè bá àwọn obìnrin àgbáyé, a sì gbà pé ó gba títẹ́tẹ̀ jára mọ́ṣẹ́ nípa ìfọkànsì, ìrètí, ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìbákẹ́dùn nísinsìnyìí ní sẹ́ńtíúrì tó ń bọ̀

## A TÚN ṢE ÌPINNU ÌSAPÁ WA LÓRÍ:

8. Ẹ̀tọ́ déédé, ògo obìnrin àti ọkùnrin pẹ̀lú àwọn kókó ojúṣe àti òfin mìíran tí ó wà nínú ìwé òfin Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé, ìwé ìpinnu ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn pẹ̀lú àwọn ohun èèlò ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lórílẹ̀-èdè káàkiri; pàápàá jùlọ ìpàdé gbogbogbò tó dá lórí ìfòpin sí gbogbo ìwà dídẹ́yẹ sí àwọn obìnrin, ìpàdé gbogbogbò lórí ẹ̀tọ́ ọmọdé, ìwé ìpinnu lórí ìfòpin si ìwà ìpánle sí àwọn obìnrin àti ìwé ìpinnu lórí ẹ̀tọ́ lori idagbasoke.

9. Láti jẹ kí ẹ̀tọ́ obìnrin pẹ̀lú ti àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin jẹ wa lógún gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò ṣe é fọwọ yẹpẹrẹ mú, kókó kan pàtàkì tí kò ṣe é yọ kúrò nínú ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àti ẹ̀tọ́ òmìnira.

10. Lórí ìpinnu àti ìlọsíwájú tó wáyé ní àwọn ìpàdé gbogbogbò ti Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé ṣe lórí obìnrin ní Náìróbì ní ọdun 1985, lórí ọ̀rọ̀ àwọn ọmọ tó wáyé ní ìlú New York nì ọdun 1990, lori agbègbè àti ìdàgbàsòkè ni Rio de Janeiro nínú

ọdun 1992, lórí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní Vienna ni ọdun 1993, lórí ìkànìyàn àti ìdàgbàsókè ni Cairo ní 1994, lórí ìdàgbàsókè àwùjọ ní Copenhagen ní 1995, lórí èrò àti ri iṣẹ́ déédé, ìdàgbàsókè àti ìbàlẹ̀ ọkàn.

11. Láti ri àmúlò àwọn ètò ìdàgbàsókè obìnrin tó wáyé ní Nairobi.

12. Ìfúnlágbára àti ìdàgbàsókè obìnrin, ètò láti ronú, lórí ẹ̀rí ọkàn, ẹ̀sìn, ìgbàgbọ́ láti ṣe àlékún ìwà ọmọlúàbí àti ọgbọ́n obìnrin àti ọkùnrin, yálà lẹ́yọ ẹnikan tàbí ọ̀pọ̀ èèyàn láti gbé ògo wọn ga kí wọ́n sì gbé ìgbé ayé wọn bí ó ti wù wọ́n lọ́kàn.

13. Agbára obìnrin àti ipa wọn lọ́nà kan náà pẹ̀lú ọkùnrin ni gbogbo iṣẹ́ ojoojúmọ́ àwùjọ, nínú ètò ìṣèpinnu, ẹ̀tọ́ sí agbára jẹ́ ọ̀nà tí ìṣedéédé lè fi wà, pẹ̀lú ìdàgbàsókè àti ìbàlè ọkàn.

14. Ẹ̀tọ́ obìnrin ni ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn.

15. Ẹ̀tọ́ déédé, lóri àwọn ohun ìní, pínpín àwọn ẹ̀tọ́ inú ẹbí ni dọgba - rí - dọgba láàrin ọkùnrin àti obìnrin, ìfẹ̀gbẹ́-kẹ̀gbẹ́ láàrin àwọn mejeeji n mu ìdàgbàsókè bá wọn àti ẹbí wọn.

16. Mímú ìṣẹ́ lọ sókun ìgbàgbé nípa okòwò tó fẹsẹ̀ múlẹ̀, ìdàgbàsókè agbègbè, ìdáàbòbò ayíká àti ìṣedéédé ní ṣe pẹ̀lú ìṣapá àwọn obìnrin nínú ètò ọrọ̀ ajé àti ìdàgbàsókè agbègbè, àǹfààní kan náà pẹ̀lú àwọn ọkùnrin àti ipa tó kún laarin obìnrin àti ọkùnrin gégé bí aṣojú àti agbẹ̀tọ́ lóri ètò ìdàgbàsókè tó múná dóko.

17. Mímọ ẹ̀tọ́ gbogbo obìnrin fún wọn láti ṣe ohun tó tọ́ lórí ètò ilera wọn pàápàá jùlọ lórí ètò ọmọ bíbí jẹ́ kókó kan nínú ètò ìfúnni lágbára wọn.

18. Ìfọ̀kànbalẹ̀ àdúgbò, orílẹ̀-èdè, agbègbè àti àgbáyé máa ṣeése bí a kò bá fọwọ́ rọ́ ìdàgbàsókè àwọn obìnrin sẹ́yìn tori àwọn ni wọ́n jẹ́ igi lẹ́yìn ọgbà fún ètò ìdarí-ìlú, ìparí aáwọ̀ àti ìfọ̀kànbalẹ̀ ni gbogbo ọ̀nà àti ààyè.

19. Ó ṣe pàtàkì láti ṣe, kí á sì tẹ̀lé àwọn ètò tó múná dóko kan lórí ọ̀rọ̀ olóbìnrin sọ̀kùnrin dé, àwọn ètò tó jẹmọ́ ìdàgbàsókè ni gbogbo ààyè; èyí ti yóò mú ìlọsíwájú àti ìdàgbàsókè bá àwọn obìnrin.

20. Ìsapá àti ìkópa àwọn èèyàn lórísìírísìí nínú àwùjọ, pàápàá jùlọ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin àti àwọn ẹgbẹ́ mìíran gbogbo ni àyíká, pí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú ìjọba ṣe pàtàkì láti jẹ́ kí àwọn eto ti ìjokòó yìí gbé kalẹ̀ ṣeé ṣe kí àbẹ̀wò sì máa wà lóòré kóòré.

21. Láti lè jẹ́ ki àwọn ètò tí a gbe kalẹ̀ yìí jẹ ṣíṣe, ìjọba orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan àti ti orílẹ̀-èdè sórílẹ̀-èdè gbodo runpá runsẹ̀ sí i. Kí wọ́n sa ipá wọn gbé àwon ètò kalẹ̀, pẹ̀lú àwọn ètò ti ìpàdé yìí ti gbé kalẹ̀, kí wọ́n sì rí àwọn ètò tí wọ́n bá ṣe gẹ́gẹ́ bí ohun tó yẹ jùlọ fun ìdàgbàsókè àwọn obìnrin.

## A TI SETÁN LÁTI:

22. Túbọ̀ sa ipá wa láti rí àmúlò àwọn ètò tó jẹ́ àgbékalẹ̀ ni Náírobì fún ìdàgbàsókè àwọn obìnrin nígbà tí sẹ́ńtíúrì yìí bá fi máa parí.

23. Láti rí i pé àwọn obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin ń gbádùn àwọn ètò ọmọnìyàn àti ètò òmìnira, kí á sì gbé àwọn ìgbésẹ̀ kan-láti fìyà jẹ ẹnìkẹ́ni tó bá tàpá sí àwọn òfin ètò àti ètò òmìnira wọ̀nyí.

24. Sa gbogbo ipá láti fòpin sí dídẹ́yẹ sí àwọn obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin, kí wọ́n sì mú gbogbo ohun tí ó bá le jẹ́ bí òkè ìṣòro kúrò lọ́nà fún ẹ̀tọ̀ déédé, pẹ̀lú ìdàgbàsókè àti ìlọsíwájú obìnrin.

25. Fún àwọn ọkùnrin ni ìwúrí láti kópa dáradára nínú àwọn ètò tó bá jọ mọ́ ìṣedéédé.

26. Mú ìlọsíwájú bá òmìnira àwọn obìnrin lórí ètò ọrọ̀ ajé, iṣẹ́ ṣíṣe, kí a sì fòpin sí ìṣẹ́ tó mú wọn dàrú nípa wíwo àwon ohun tó ń fa ìṣẹ́, kí á le ṣe àtúntò ètò ọrọ̀ ajé, fún àwọn obìnrin láì yọ àwọn tìgbèríko sẹ́yìn. Kí wọ́n sí ní ààyè gẹ́gẹ́ bí akópa nínú ètò ìdàgbàsókè àwọn ohun ọrọ̀ ajé gbogbo àti ètò ìsìnro ilu.

27. Mú ìlọsíwájú bá ìdàgbàsókè pẹ̀lú ẹ̀tò ọrọ̀ ajé tó múná dóko nípa ìpèsè ẹ̀kó tó dájú, ètò mò ọ́n kọ, mọ̀ ọ́n kà àti ètò ìlera fún àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti àwọn obìnrin lápapọ̀.

28. Gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó máa mú ìfòkànbalẹ̀ wà, èyí tí yóò ṣe okùnfà ìdàgbàsókè àwọn obìnrin kí wọ́n sì rí ipa pàtàkì tí àwon obìnrin ti kó nínú ètò ìfòkànbalẹ̀, ìṣẹ́ àṣekára nípa àwọn ètò tó yanjú nínú Àjọ Orílẹ̀-Èdè. Láti gbé òfin dìde lórí lílo àwọn ohun ìjà olóró ní ìlòkulò tàbí ṣíṣe àyẹ̀wò àwon ohun ìjà náà láì bìkítà.

29. Fòpin sí gbogbo ìwà ìpánle sí àwọn obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin.

30. Jẹ́ kí àwọn obìnrin náà ní ẹ̀tọ́ gẹ́gẹ́ bí ọkùnrin sí ètò ẹ̀kọ́ àti ìlera pàápàá ètò ìlera lórí ìṣabiamọ àti ẹ̀kó.

31. Ṣe àgbélárugẹ àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn tó jẹ́ ti obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin.

32. Tẹra mọ́ ìsapá láti rí pé awọn obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin gbogbo tí wọn kò tíì rí ẹ̀tọ́ wọn gbà fún ìdí kan tàbí òmíràn nípa ẹ̀yà, ọjọ́ orí, èdè, àṣà, ẹ̀sìn, yálà nítorí jíjẹ́ abirùn tàbí pe won je omo abinibi ibikan je adun awon ẹ̀tọ́ ati ètò òmìnira wọ̀nyí lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́.

33. Ríi pe ọ̀wọ̀ wà fún òfin Àjọ orílẹ̀-èdè, pẹ̀lú òfin ọmọnìyàn láti dáàbò bo àwọn obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin.

34. Jẹ́ kí ìdàgbasókè bá àwọn ẹ̀bùn oríṣiíríṣi tí àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti obìnrin gbogbo ní, kí wọ́n kó ipa kíkún nínú sísọ ìgbé ayé di rere fún àwọn ènìyàn ayé gbogbo, kí ipa wọn nínú iṣẹ́ ìdàgbàsókè lè yọ.

## A TI PINNU LÁTI:

35. Jẹ́ kí àwọn obìnrin ní ẹ̀tọ́ sí àwọn ohun èèlò ọrọ̀ ajé ilẹ̀, ètò ìyàwó, ìmọ̀ sáyẹ̀nsí àti iṣẹ́ ẹrọ, ẹ̀kọ́ iṣẹ́ ọwọ́ ètò ìròyìn, àti ọjà gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀na tí ìlọsíwájú àti ìdàgbàsókè fí máa bá àwọn obìnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin, pẹ̀lú mímú ìlọsíwájú bá àwọn ohun tí ipa wọn ka fún ìgbádùn àwọn ètò wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹnìkejì wọn nípa ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Àjọ Orílẹ̀-Edè.

36. Rí àṣeyọrí ìwé àbádòfin lórí ìlànà àtẹ amúṣẹ́ṣe "(Platform for Action)" èyí tó ní ṣe pẹ̀lú ìsapá àwọn ìjọba gbogbo, àwọn Àjọ Orílẹ̀-Èdè pẹ̀lú ẹgbẹ́ lọ́kan ò-jọ̀kan. A ní ìdánilójú pé ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀ ajé, ìhùwàsí, láwùjọ, pẹ̀lú ìdáàbòbò agbègbè, wọnú ara wọn. Àwọn wọ̀nyí náà ni ó sì lè mú ìdàgbàsókè gidi wà, èyí tí ó jẹ́ lájorí gbogbo ipa tí à ń sà láti rii pé ìgbé àyé dẹrùn fún àwọn ènìyàn. Ìdàgbàsókè àwùjọ tó ń rí sí ìlọsíwájú àwọn alàiní, pàápàá jùlọ àwọn obìnrin tí wọ́n ń gbé nínú ìṣẹ́; lílo àwọn ohun ìní tó wà láròówótó jẹ́ òpómúléró fún ìdàgbàsókè àwùjọ àti

ètò ìṣedéédé láwùjọ. Kí ètò ìgbékalè àbádòfin yìí tó lè ní àṣeyọrí, ètò gbọdọ̀ wà fún àkojọ àwọn ohun èèlò páàpáà owó láti ran àwọn orílẹ̀-èdè, àgbègbè àti Àjọ Orílẹ̀-Èdè lọwọ́ nínú ìsapá wọn fún ètò ìsedéédé, ètò déédé, pínpín ojúṣe déédé àti níní àǹfàání bákan náà kí àwọn obìnrin àti ọkùnrin sì lè kópa bákan náà ní Àjọ Orílẹ̀-Èdè, àdúgbò àti ní orílẹ̀-èdè nínú àwọn ètò òfin ṣíṣe. Kí wọ́n sì jọ ṣe àgbékalẹ̀ ètò ìjábọ̀ gbogbọgbò fún àwọn obìnrin.

37. Jẹ́ kí àṣeyorí wà fún Àtẹ Amúṣéṣe yìí ní àwọn orílẹ̀-èdè tí ọrọ̀-ajé wọn kò bá gúnrégé, èyí tı ó máa fẹ́ ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìrànlọ́wọ́ láàrin àwọn orílẹ̀-èdè.

38. Ní báyìí a ṣe àgbékalẹ̀ àti ìpinnu wa gẹ́gẹ́ bí ìjọba gbogbo láti ṣe àmúlo àbádòfin yìí, kí a sì ri i pé ọ̀rọ̀ ọ̀dọ́kùnrin sóbìnrin ń jẹ́ àgbéyẹ̀wò nínú gbogbo òfin àti ètò wa. À rọ Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé ẹgbẹ́ ìkówójọ ní agbègbè àti àjọ àgbáyé, àwọn ẹgbẹ́ mìíran tó bá tún tọ́ sí ní àgbáyé, àwọn obìnrin àti ọkùnrin, pẹ̀lú àwọn oníṣẹ́ àdáni gbogbo, àwọn oníṣẹ́ ìjọba ní ìfọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú ìjọba, kí wọ́n sa ipá wọn láti dá sí gbígba àbádòfin yìí wolé, kí ó sì di àmúlò.

## ÀTẸ AKITIYAN (ÌṢỌNÍSÓKÍ) ÈRÒŃGBÀ, ÌGBÉSẸ̀, AKITIYAN

Láti ìgbà tí Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé ti se ìpàdé àkọ́kọ́ lórí àwọn obìnrin ní ogún ọdún sẹ́yìn ní ìlú Mexico lọ́dún (1975), ní ìlọsíwájú tó ṣe pàtàkì ti wáyé lórí ìṣedéédé láàrin àwọn obìnrin àti ọkùnrin. Ètò àwọn obìnrin sí ètò ẹ̀kọ́ pẹ̀lú ìlera ti gbòòrò si i. Wọn ti ń pọ̀ si i lẹ́nu iṣẹ́ ojúmọ́ àṣejẹun. Àwọn òfin tó ń ṣe ìlérí àǹfààní déédé pẹ̀lú ọkùnrin fún àwọn obìnrin àti ọ̀wọ̀ fún ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn wọn, ní ọ̀pọ̀ orílẹ̀ èdè ti ṣe. Nídìí èyí, àwọn ìyàtọ̀ ọlọ́kan o-jọ̀kan tí ń wáyé láàrin obìnrin àti ọkùnrin.

Síbẹ̀, ìdẹ́yẹ sí àwọn obìnrin sì pọ̀ káàkiri. Ìwà ìpánle sí obìnrin jẹ́ ohun tó gbèrú lágbàáyé. Ẹtọ́ won sí àwọn ohun èèlò si níwọ̀n, nígbà tí ànfààní tí wọ́n ní sí ẹ̀kọ́ gíga àti ètò ìkọ́ṣẹ́ mọ ní àwọn iṣẹ́ kan. Gaga kan sì ń dí ìdàgbàsókè àwọn òbìnrin nínú iṣẹ́ ìsòwò, ìṣèjọba àti ìṣèlú. Ìyàlẹ́nu ló jẹ́ pé àwọn obìnrin ló pọ jù nínú bíi bílíọ̀nù kan àwọn ènìyàn tí iṣẹ́ mù dáru, tí wọn kò sì mò ọ́n kọ tàbí mọ̀ ọ́n kà. Ọ̀pọ̀ ìpinnu tí ó jẹ mọ́ àwọn obìnrin ni ó jẹ́ pe ọkùnrin ló ń se wọ́n.

Ìpinnu Beijing pẹ̀lú àbádòfin tó di àgbékalẹ̀ ní ìpàdé àgbáyé kẹrin lórí àwọn obìnrin (4-15 Sept., 1995) láàrin àwọn aṣojú láti orílẹ̀ èdè mọ́kàn-dín-láàdọwà fi ìpinnu àjọ orílẹ̀-èdè titun hàn sí ìṣedéédé, ìdàgbàsókè àti ìfọkànbalẹ̀ fún gbogbo obìnrin káàkiri àgbáyé.

Ìwé àbádòfin náà, tí a pín sí orí mẹ́fà, ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn nǹkan tó ń ṣe ìdíwọ fún ìdàgbàsókè àwọn obìnrin. Ó sàlàyé àwọn èròngbà, ó sì sọ àwọn akitiyan tó máa jẹ́ ṣíṣe láti ìsinsìnyi di bí ọdún márùn-ún sí àsìkò tí a wà yìí lọ́wọ́ ìjọba, Àjọ Orílẹ̀-Èdè, àwọn àjọ aládàáni, pẹ̀lú àwọn oníṣẹ́ àdáni láti mú àwọn ìṣòro wọ̀nyí kúrò.

Ìtẹnumọ́ tún wà fún àbá nínú ìpinnu Beijing. Ó sọ ìpinnu àwọn ìjọba láti sa ipá wọn kí ìwà ìdẹ́yẹ sí àwọn obìnrin le lo sókun ìgbàgbé, kí gbogbo ìṣòro tó dojú kọ ìṣedéédé si kúrò. Wọ́n tún ń ìdí tí ó fi yẹ kí wọ́n máa fi ojú àgbà wo gbogbo ohun tó bá jọ mọ́ ọ̀rọ̀ obìnrin sọkùnrin nínú gbogbo òfin àti ètò wọn.

## Ọ̀RỌ̀ LÓRI ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀMÚLÒ RẸ̀ LÁGBÀÁYÉ

Láti ìgbà tí ìpàdé tó wáyé ní Náíróbì ní ọdún 1985 lóri obinrin ti wáyé ni àwọn ìyàtọ ti ń selẹ̀ ni àgbáyé, yálà fún ànfààní tàbí ìpálara àwọn obìnrin. Àjọ kan dìde tó ń ṣe àgbéyẹ̀wò ìkópa gbogbo ènìyàn nínú ètò ìṣèlú àgbáyé ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀-èdè. Ìṣọwọ́ dìde

ẹgbẹ́ obìnrin oríṣìíríṣìí ti di ohun to ń ta àwọn ènìyàn jí fún ìyàtọ̀ ọlọ́kan-ò-jọ̀kan.

Bákan náà ni ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ ajé tí kò fara rọ, ètò ìṣèlú tí kò dúró déédé, ìnákúnàá àwọn ológun, àwọn ètò ìpadàbọ̀ sípò orílẹ̀ èdè púpọ̀ tó mẹ́hẹ, àsan tún san owó èlé lórí gbèsè ilẹ̀-òkèèrè, àti ìbàjẹ́ agbègbè lójoojúmọ́ jẹ gbòǹgbò ìpalára fún àwọn obìnrin. Ìwé àtẹ akitiyan, ètò tó wà fún ìlọsíwájú àwọn obìrin, fẹ́ ṣe àtúnṣe gbogbo nǹkan wọ̀nyí. Ó ń fẹ́ láti wá ìlọsíwájú àti ìdáábò bò gbígbádùn gbogbo ètò ọmọnìyàn àti ètò òmìnira gbogbo àwọn obìnrin ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn. Ó tún ń pe ìpè fún ṣíṣe òfin tó máa fi ìdí àjọpín agbára àti ojúse múlẹ̀ láàrin obìnrin àti ọkùnrin nínú ilé, níbi iṣẹ́ àti ni orílẹ̀-èdè pẹ̀lú àjọ orílẹ̀ èdè gbogbo.

Láti mú kí akitiyan yìí, kógo já, àwọn ìjọba gbogbo, Àjọ Orílè-Èdè àti àwon ẹgbẹ́ gbogbo nílati sa ipá wọn ní gbogbo ọ̀nà. Ótún máa gba ki wọn ko àwọn ohun èèlò jọ ni gbogbo ààyè tó bá yẹ pẹ̀lú àfikún fún àwọn orílẹ̀ èdè tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń gòkè àgbá.



Ìṣẹ́ ati àìní ti wo awọn obìnrin lọ́rùn: Àwùjọ wa gbọ́gọ̀ dẹ́kun ìṣẹ́ ati àìríná àwọn obìnrin fún ìrọrùn gbogbo-gbòò.




Agbòòrùn òfin. O lè di ohunkóhun tí o bá fẹ́ ńwọ̀n ìgbà tí o bá ti ní ìmọ̀ ẹ̀kọ́ tó yè kóoro. Kò sí wàhálà lorii bóyá abo ni ọ́ tàbí akọ.

## ÈTÒ Ẹ̀KỌ́ ÀTI ÌKỌ́NI

Ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ni ẹ̀kọ́ jẹ́, ó sì jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ohun èèlò tó ń mú ìṣedéédé, ìdàgbàsókè àti ìfòkànbalẹ̀ wá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pe ìlọsíwájú ti wà nínú ìforúkọsílẹ̀ àwọn obìnrin ní ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti ti girama, àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin ni ọ̀pọ̀ orílẹ̀-èdè ni wọ́n sí ń fi ẹ̀tọ́ wọn dùn nítorí àṣà fífa ọmọ fọ́kọ ni kékere, oyún, àìsí àwọn ilé ìwé tó yẹ pẹ̀lú àìtó ẹ̀kọ́ àti ohun èèlò ẹ̀kọ́ fún ìmọ̀ lóri ìṣedéédé obìnrin àti ọkùnrin. Àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin kò rí ẹ̀kọ́ tó yé kooro gbà, pàápàa jùlọ ètò ẹ̀kọ́ gíga, àti nínú ìmọ̀ sáyẹ̀nsí pẹ̀lú ìmọ̀ ẹ̀rọ. Nínáwó sí ojú ọ̀nà ẹ̀kọ́ ìgbàlódé àti ti àdáyébá pẹ̀lú onírúurú ètò ìkọ́ni fún àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti àgbàlagbà obìnrin ti fojú hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà kan tó ṣe pàtàkì jù láti rí ìdàgbàsókè àti ìgbèrú ọrọ̀ ajé.

## ÀTẸ AKITIYAN DÁBÀÁ ÀWỌN ÌGBÉSẸ̀ TÓ LÈE:

- Fa ẹ̀tọ́ deede sí ètò ẹ̀kọ́. Àwọn ìjọba gbọdọ̀ sa ipá wọn ní ọdún márùn-un sí ìgbà tí a wà yìí, sí ẹ̀tọ́ gbogbo ọmọ, sí ẹ̀kọ́ tó ṣe kókó jù, kí wọn rii pé ìdá ọgọ́rin ó kéré jù nínú ìdá ọgọ́rùn -ún àwọn ọmọ tó ti tó ilé ìwé lọ parí ẹ̀kọ́ ilé-iwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Wọ́n tún gbà láti dí àwọn àfo tó wà láàrin ẹ̀kọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti ti girama ní ọdún márùn-ún sí àsìkò yìí kí won sì rii pé ọ̀pọ̀ ti ní ẹ̀kọ́ ni gbogbo orílẹ̀-èdè nígbà tí a bá fi máa ní ogún ọdún si àsìkò yìí.

- Pa àìmọ̀ ọ́n kọ,mọ̀ ọ́n kà rẹ́ láàrin obìnrin. Àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ dín iye àwọn obìnrin tí kò mọ̀ ọ́n kọ-mọ̀-ọ́n kà kù bí ààbọ̀ iye tí wọn jẹ́ o kéré pin ní ọdún márùn-ún sẹ́yìn.

- Jẹ́ kí ìlọsíwájú bá ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin sí iṣẹ́ ọwọ́, ẹ̀kọ́ sáyẹ́nsì, ìmọ̀ ẹ̀rọ àti ètò ẹ̀kọ́ ìgbà yìí láàrọ.

- Mú ìdàgbàsókè bá ètò ẹ̀kọ́ àti ìkọ́ṣẹ́ ọwọ́ láì sí ìyapa.

* Ṣe ìpèsè ànító ohun èèlò àti àmójútó ìmúlò àwọn ètò ẹ̀kọ́.

* Mú ìlọsíwájú bá ẹ̀kọ́ àti ètò ìkọ́ṣẹ́ fún àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti àwọn obìnrin.




Àláàfíà tara, tẹ̀mí topọ lọ ṣe pàtàkì fún ìgbà ayé obìnrin'

## ÈTÒ ÌLERA

Ìlera àwọn obìnrin ní ṣe pẹ̀lú èrò, àwùjọ àti gbogbo ara wọn. Tí àwùjo, ìṣèlú àti ọrọ̀ ajé wọn bá gbè wọ́n, ìlera a bá won, bẹ́ẹ̀ sì ni ẹ̀kọ́ ìmọ̀ nípa ẹ̀dá ọmọnìyàn. Gbígbádùn lọ́nà tó ga jù ní ti ara àti ọpọlọ ṣe pàtàkì fún ayé àti àláàfíà àwọn obìnrin. Ó tún ṣe pàtàkì fún wọn láti lè kópa ni gbogbo ọ̀nà yálà láwùjo àti sí ìgbésí ayé ara wọn. A gbọ́dọ̀ bá won dáàbò bo ẹ̀tọ́ yìí ni gbogbo ìgbésí ayé wọn lọ́nà kan náà pẹ̀lú àwọn ọkùnrin.

Ìwé àtẹ akitiyan yìí sàlàyé ìlera to wúlò gẹ́gẹ́ bí àyè tí ìlera ti wà fún àgọ́ ara, ọpọlọ àti àwùjọ pẹ̀lú ìbálòpọ̀ obìnrin sọkùnrin lórí ọ̀rọ̀ ìlòpọ̀ àti ìsabiamo tó fẹ́ ọ̀wọ̀ láti ọwọ àwon méjẹ́ẹ̀jì, gbígba àṣẹ lọ́wọ́ ara wọn àti àjọpín ojúṣe. Ìwé àtẹ yìí ní mọ̀ pe ètò ìsabiamo dá lórí mímọ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn gbogbo tọkọtaya, àti oníkálukú, láti pinnu lómìnira ara rẹ̀ láì jẹ pẹ́ wọn fi dandan mu un, iye ọmọ tó fẹ bí àti ìgbà tí ó fẹ́ bi wọn. Wọ́n tún ní ẹ̀tọ́ láti gba ìmọ̀ kún ìmọ̀ wọn kí wọn sì ṣe ìpinnu lórí ìsabiamọ wọn láì sí ìyapa tàbí fífi ipá mú ẹnikẹni.

## ÀTẸ AKITIYAN YÌÍ DÁBÀÁ ÀTI:

* Ṣe àlékún ẹ̀tọ́ àwon obìnrin títí ayé, sí ètò ìlera tó tọ́, tí ipá wọn máa ká àti èyí tí ó dára jùlọ fún wọn. Ṣíṣe ètò ìmọ̀ nípa ìlera àti àwọn ètò mìíràn tó jẹ mọ́ ọn.

* Dín iye àwọn obìnrin tó ń kú lórí ìkúnlẹ̀ kù bí ìdajì iye tí wọ́n jẹ́, ó kéré jù ni ọdún márùn-ún sẹ́yìn tí á bá fi máa ri ọdún márùn-ún sí àsìkò yìí kí ó sì tún din bí ìdajì sí i nígbà tí a bá fi máa ń ogún ọdún sí àsìkò yìí.

* Ṣe ìwúrí fún àwọn obìnrin àti ọkùnrin láti gba ojúṣe tí ó bá ti ibi ìlòpọ̀ àti ìsabiamọ wọn jáde.

* Ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ètò tó máa dá lórí àwọn àrùn tó ń ti ibi ìlọ̀pọ̀ ọkùnrin àti obìnrin jáde pẹ̀lú àwọn tó ń ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìlera ṣíṣabiamọ

* Ṣe alékún àwọn ohun èèlò ìmójú-tó ètò ìlera fún àwọn obìnrin.



Ìwà ẹrankoníyan ni láti máa lo obìnrin nílòkulò. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà ló wà téniyàn fi lè wojútú sí Ìṣòro

## ÌWÀ ÌPÁNLE

Ní gbogbo àwùjọ pátá lọ́nà kan tàbí òmíràn ni ẹ̀gbin orísìírísìí ti ń gun àwọn obìnrin lórí ara wọn; ilopọ̀ wọn pẹ̀lú àwọn ọkùnrin, àti ẹ̀gbin tó ní ṣe pẹ̀lú ẹ̀mí àti èrò wọn láì dá ẹ̀yíkẹ́yìí sí nínú wọn yálà ó lówó àbí ipò kan ni; nínú àṣà, nínú àwùjọ tàbí nínú ilé wọn. Wọn máa ń fi ipá bá wọn lò ni ọ̀pọ̀ ìgbà, ẹ̀gbin orisirisi tó jẹ́ mọ́ ìlòpọ̀ lẹ́nu iṣẹ́. Àwọn ni wọ́n ń jẹ ọ̀pọ̀ ìyà jù lásìkò ogun. Mímú lẹ́nú, oyún ipá, ìsọdàgàn àti ṣíṣẹ́ oyún ni dandan; níní àsepọ̀ ọ̀dọ́mọde obìnrin pẹ̀lú ọkùnrin láì tó àsìkò àti pípa àwọn ọmọbìnrin ni ìkọ̀kọ̀, jẹ́ ìwà ìpánle si àwọn obìnrin. Gbogbo àwọn ìwà ìpánle sí obìnrin yìí jẹ́ ìwà ọ̀daràn tí ó tàpá sí ìgbádùn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn pẹ̀lú ẹ̀tọ́ òmìnira wọn. Àwọn ìṣòwò Obìnrin tí wọn máa ń lọ ṣiṣẹ́ kiri ní ìlú onílùú ni ó fẹ́ àkíyèsí wa jù, torí àwọn ni wọ́n máa ń sáàba ṣàgbákò irú àwọn nǹkan wọ̀nyí.

Àìsí òfin ìdáàbòbò tó de irú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyí pẹ̀lú àìsí ẹ̀tọ́ àti ìfimúlẹ̀ àwọn òfin wọ̀nyí láti ọwọ́ àwọn àgbófinró nínú ìlú jẹ àtọ́kùn ìfìyà jẹni fún àwọn obìnrin kódà, bí irú òfin bẹ́ bá wà.

## ÀTẸ AKITIYAN YÌÍ DÁBÀÁ ÀWỌN ÌGBÉSẸ̀ YÌÍ:

* Kí àwọn ìjọba ṣe òfin, kí wọ́n sì fi ìdí irú òfin bẹ́ múlẹ̀ láti dẹ́kun àwọn ìwà ìpánle sí obìnrin.

* Iṣẹ́ àṣekára láti fòntẹ̀ tẹ àwọn ìpinnu lágbàyé kí wọn sì fi irú àwọn ìpinnu Àjọ Àgbáyé bẹ́ẹ̀ múlẹ̀ tó dá lé ìwà ìpánle sí àwọn obìnrin, pẹ̀lú ìpinnu ìpàdé àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé lórí fífòpin sí gbogbo ìwà ìdẹ́yẹ sí àwọn obìnrin.

* Ìpèsè ààbò ìrànlọ́wọ́ òfin àti àwọn ẹ̀tọ́ mìíràn fún àwọn abilékọ àti obìnrin tí ìṣòro ń kojú, ki wọ́n si pèsè ètò ìgbaninímọ̀ràn, ìtọ́sọ́nà àti ààyè ìfiniwọ̀ fún àwọn tó bá kúndùn ìwà ìpánle sí àwọn obìnrin

* Ki àwọn oníle-ẹ̀dẹ̀ àti Àjọ Oníle-Èdè sowọ́pọ̀ láti tú àwọn ètò tí àwọn kan ṣe láti lo obìnrin fún àwọn iṣẹ́kíṣẹ́ ká.



**Ìfipá bara-ẹni lòpọ̀ lásìkò rògbòdìyàn: Ìfipá múni-básùn jẹ́ gbògbò ẹ̀ṣẹ̀, kódà lásìkò ogun.**

Ìbàlẹ̀ ọkàn jẹ ohun kan pàtàkì láti rí ìsedéédé láàrin obìnrin àti ọkùnrin. Ṣùgbọ́n ìbànújẹ́ ló jẹ́ láti rí pé ogun àti àwọn aáwò oríṣiríṣi sì wà káàkiri àgbáyé. Wàhálà fífà, gbígba i.é onílé láìtó, ìjà ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti oríṣiiríṣií aáwọ̀ jẹ́ àwọn nǹkan tí ó ń dàamú àwọn obìnrin káàkiri àgbáyé, pẹ̀lú ìnákúnàá àwọn ológun àti owó ohun ìjà.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn obìnrin kìí sáábà sí níbi ìpinnu tó ń mú ìjà wá, síbẹ̀ wọn máa ń sa ipá wọn láti mú àlàáfíà bá àwùjọ kí òpin sì bá aàwọ̀ yóowù tó bá wà. Wọ́n tún ń kó ipa pàtàkì gẹ́gẹ́bí olùdámi lẹ́kọ̀ọ́ lorí ìfọ̀kànbalẹ̀ àti ìfòpin sí aàwó.

Ìwé àtẹ akitiyan yìí rí mọ̀ pé fifi ipá bá obìnrin lò pọ̀, èyí tí ó máa ń wọ́pọ̀ lásìkò ogun jẹ́ ìwà ọ̀daràn àti nígbà míìràn lè jẹ ìwà ìpanirun. Ó bu ẹnu àtẹ́ lu pípa àwọn èyà kan rẹ́ gẹ́ẹ́ bí ìgbésẹ̀ ogun àti ìfipá bá obìnrin lò gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn ohun tó lè fàá. Irú àwọn ìwà bàyí gbọ́dọ̀ dópin kí àwọn tó bá ń hu irú rẹ̀ sì gba ìdájọ́ tó yẹ.

## ÀTẸ AKITIYAN YÌÍ DÁBÀÁ ÌGBÉSẸ̀

* Ṣíṣe àlékún ipa tí àwọn obìnrin ń kó nínú pípaŕí aàwọ́ nípa fífi wọ́n sí ibi ìpinnu ṣíṣe.

* Didín ìnákúnàá àwọn ológun kù, kí wọ́n sì din àwọn ohun ìjà olóró kù pẹ̀lú.

* Ìgbìyànjú láti mú àbá lórí ẹ̀sùn ìpànle tó wáyé níbi ìpàdé àgbáyé ṣẹ ni ọdún márùn-ún sí àsìkò yìí.

* Mímọ ipa pàtàkì tí àwọn obìnrin ń kó lórí èrò ìfọ̀kànbalẹ̀ káàkiri àgbáyé.

* Mímọ̀ pé ó yẹ láti dáàbò bo àwọn obìnrin tó ń gbé nínú ogun àti àwọn aàwọ míràn, tàbí tí wọ́n ti di aláìnílé àti ayálégbé ni ìlú ibòmiràn.



Ẹ̀tọ́ ni dọ́gba-ń-dọ́gba: Àwọn obìnrin náà lẹ́tọ̀ sí iṣẹ́ tó buyì kúnni láwùjọ, wọn kò gbọ́dọ̀ jẹ́ aṣẹ́gità àti apọnmità nìkan.

## Ọ̀RỌ̀-AJÉ

**Ipa pàtàkì** ni àwọn obìnrin ń kó nínú ètò ọrọ̀ ajé káàkiri. Wọ́n ti ń pọ̀ síi nínú iṣẹ́ àṣejẹun, wọ́n ti ń kó ipa nínú àwọn ilé-iṣẹ́ kéréje-kéréje gbogbo. Owó tí wọ́n sì ń gbà ń dí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àlàfo nínú ilé. Síbẹ̀ wọ́n sì ń yọ wọ́n sẹ́yìn nínú àwọn ìpinnu síṣe tó jọ mọ́ ti ọrọ̀-ajé. Owó tí wọ́n ń fún wọn kò jojú, àwọn ẹ̀tọ́ ẹnu iṣẹ́ kò nílaárí, nígbàtí ó sì lojú àwon ààyè tí wọ́n lè fi wọ́n sí lẹ́nu iṣẹ́ àti irú iṣẹ́ tí wọ́n máa ń fun wọn ṣe. Bi o tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn obìnrin ń lé kún ìdàgbà sókè ní iṣẹ́ tí wọn ń gbowó lé lórí àti èyí tí wọn kò gbowó lé lórí, síbè èyí tí wọn kò gbowó lé lórí gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ilé àti ti àdúgbò ni kò ní ìwọ̀n tí wọ́n gbé lé wọn, ti orílè-èdè kò si sírò wọn mọ ètò ìsúná.

Ìyapa nínu ẹ̀kọ́ àti ètò ìkọ́ṣẹ́, híhaáyà, owó iṣẹ́ àti ìgbéga lẹ́nu iṣẹ́, àwọn èto ẹnu iṣẹ́ tí kò bára mu, àìní ẹ̀tọ́ sí àwọn ohun èèlò iṣẹ́ àti àìdọ́gba pínpín ojúṣe ilé, ń mú àdínkù bá ètò ìgbani síṣẹ́, ọrọ̀-ajé àti ètò iṣẹ́ fún àwon obìnrin.

## ÀTẸ AKITIYAN YÌÍ DÁBAÁ PÉ:

- Kí wọn ṣe àlékún ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin lórí okòwò àti òmìnira wọn pẹ̀lú ẹ̀tọ́ sí iṣẹ́, ẹ̀tọ́ ẹnu iṣẹ́ tó bójú mu, àti àkóso lórí àwọn ohun èèlò ọrọ̀-ajé.
- Ṣe àlékún ẹ̀tọ́ obìnrin sí àwọn ohun èèlò iṣẹ́, ọjà, àti ètò kárà tátà.
- Pèsè àwọn ohun amúṣẹ́ṣe, ẹ̀kọ́ṣẹ́ àti ànfààní láti nájà, mímọ̀ nípa ohun tó ń lọ lóde àti ìlò ẹ̀rọ gbogbo-ǹ-ṣe pàápàá jùlọ fún àwọn abiléko olówó pọ́ọ́kú.
- Àfikún ìlànà iṣẹ́, ọrọ̀-ajé àwọn obìnrin àti àwọn ònà ìyànjú kátà-kárà wọn.
- Fòpin sí dídẹ́yẹ sí àwọn obìnrin lẹ́nu iṣẹ́, pẹ̀lú gbogbo orísiírísìí ètò fífẹ̀tọ́ ẹ̀ni dun ni nídìí ìgbani síṣẹ́.
- Ṣe àlékún déédé lẹ́nu iṣẹ́ àti àjọpín ajúṣe nínú ẹbí fún obìnrin àti ọkùnrin.



Ọlọ́gbọ́n ati ọlọ́ye l'àwọn obìnrin. Kíkópa àwọn obìnrin ninu ìpinnu ṣíṣe máa l'áseyọrí tó gún régé.

## ÌṢÈPINNU

Fífún àwọn òbinrin ni ẹ̀tọ́ kan náà nínú ìṣèpinnu kìí ṣe ohun tó dá lórí òfin ìṣedéédé tàbí ètò ìṣèlú tiwa-ń-tiwa nìkan. Ó tùn ṣe pàtàkì nínú orísìí ìjọba tí ó peregedé tí yó sìi máa lè jábò iṣẹ́ rẹ̀ fún ará ìlú. Ó tún máa jẹ́ kí déédé wà nínú àwọn ènìyàn ìlú tó ń darí ọ̀rọ̀ ìlú wọn.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ṣíṣe ìjọba ìlú ti ń bọ́ si ọwọ́ àwọn onílùú ni ọ̀pọ̀ orílẹ̀-èdè báyìí, síbẹ̀ ọ̀pọ̀ àyè nínú iṣẹ́ ìsìnlú ni àwọn obìnrin kó ti pọ̀ tó bọ ṣe yẹ, pàápàá jùlọ ní àwọn àayè ìṣàkọ́so gbogbo. Àlá Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé tó ń rí sí ọrọ̀-ajé àti tàwùjọ láti rí ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún àwọn obìnrin ni àwọn ààyé yìí ni ọdún 1995 kò ṣẹ rárá. Ìlọsíwájú díẹ̀ ni wọ́n ní nípa dídé ààyè ìṣèlú àti ti aṣòfin. Ìdá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún ló wà ní ìgbìmọ̀ aṣòfin ni gbogbo àgbáyé, nígbà tí àwọn tí ó wà nígbìmọ̀ ìṣàkóso kò tilẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ rárá.

Bẹ́ẹ̀ ná ló jẹ́ pé àìpọ̀ àwọn obìnrin nínú ìgbìmọ̀ tó ń ṣe ìpinnu lóri àwọn ọ̀rọ̀ bíi ohun ẹ̀ṣọ́ ìlú, àṣà, eré ìdárayá, ètò ìròyìn, ẹ̀kọ́, ẹ̀sìn àti òfin ń jẹ́ ìdíwọ́ pàtàkì fún àwọn òbinrin láti kó ipa pàtàkì nínú àwọn ilé-iṣẹ́ wọ̀nyí àti nípa ètò ìṣàkóso wọn.

## ÀTẸ AKITIYAN DÁBÀÁ PÉ:

- Kí won rìí pé àwọn obìnrin ní ẹ̀tọ́ dọgba-ń-dọgba láti kópa kíkún nínú ètò ìṣèpinnu, nínú gbogbo ìgbìmọ́ alábojútó iṣẹ́ ìjọba, àwọn àyè ìṣàkóso, pẹ̀lú ti ìdájọ́, ti Àjọ-àgbáyé, ilé-iṣẹ́ àdáni, àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú pẹ̀lú ti ọrọ̀-ajé.

- Ṣe àlékún agbára tí àwọn obìnrin ti ní tẹ́lẹ̀ nínù ìṣèpinnu àti ipò olóri




Àtìlẹ̀hìn owó ati ti eeto ìlú se pàtàkì fún àwọn ohun àgbekalẹ̀ tówà fún ìlosíwájú àwọn obìnrin

## ÌṢÀKÓSO ÀWỌN ÌGBÌMỌ̀

Ọ̀pọ̀ orílẹ̀ èdè ni ó ti dá àwọn ìgbìmọ̀ oríṣiiríṣi sílẹ̀ fún ìdàgbàsókè àwọn obìnrin. Àwọn àjọ yìí yapa ni oríṣiiríṣii ọ̀nà, wọn kò sì gún régé nínú ṣiṣe iṣẹ́ tí a yàn wọ́n fún. Wọn kìí fi tiwọn ṣe ni àwọn iléìjọba gbogbo, bẹ́ẹ̀ ni wọn kìí ni òṣìṣẹ́ àti àwọn ohun èèlò tó, pẹ̀lu ìfọwọ́sowọ́pọ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn adarí ìjọba. Bẹ́ẹ̀ náà ni ìṣòro wònyí ń ko jú àwọn obìnrin ní káàkiri orílẹ̀ èdè àyé.

Ọ̀pọ̀ ọgbẹ́ ni ó ṣe ètò fún ìtúpalẹ̀ ọ̀rọ̀ obìnrin sọ́kùnrin, ṣùgbọ́n ìbànújẹ́ ló jẹ́ pé ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan ni àwọn míràn ń ṣe àmúlò ètò yìí nígbà tí àwọn míràn kò tilẹ̀ kọbi ara síi rárá.

## ÀTẸ AKITIYAN YÌÍ DÁBÀÁ PÉ:

* Ṣíṣe àgbékalẹ̀ tàbí àlékún agbára àwọn irinṣẹ́ àti àjọ tó ń ṣe ìjọba; kí wọ́n rii pé ojúṣe ìdàgbàsókè àwọn obìnrin bọ́ sí ọwọ́ àjọ tó ga jù nínú ètò ijọba ṣíṣe.

* Ṣe àfikún ọ̀rọ̀ lọ́kùnrin-lóbìnrin sínú ètò òfin, ètò ìṣàkọso àwùjọ, àwọn ètò àti iṣe gbogbo tí wọ́n gbé kalẹ̀, kí wọn sì rii pé wọ́n ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn ìpinnu tí wọ́n bá fẹ́ ṣe láti wo bí ó ṣé máa bá obìnrin àti ọkùnrin wi, kí wọ́n tó ṣe irú ìpinnú bẹ́ẹ̀.

* Ṣe àgbékalẹ̀ àwọn àtẹ àti ètò ìròyìn fún ìṣètò àti ìgbéléwọ̀n, kí wọ́n mọ ríri àwọn iṣẹ́ tí kò sí nínú ètò ìsúná ìjọba ní bí wọ́n ṣe pọ̀ tó.



Àparò kan kò ga ju kan lọ laarin ọkùnrin sóbìnrin: Kò gbọ́dọ̀ si ẹlẹ́yàmẹ̀yà ninu ètò lórí iṣẹ́ àti ojúṣe.

## ẸTỌ́ ỌMỌNÌYÀN

Gbogbo ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ló kárí àyé, tí kò ṣeé pín wẹ́wẹ́ bẹ́ẹ̀ ni wọn wọnú ara won. Rírí pé àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti obìnrin pàápàá jẹ adùn rẹ ni kíkùn àti ní ọ̀nà kan náà pẹ̀lú àwọn ọkùnrin. Wọ́n gbọ́dọ̀ jẹ ìjọba gbogbo lógún, pẹ̀lú Àjọ-Ìṣọ̀kan-Àgbáyé, torí kókó kan pàtàkì ló jẹ́ fún ìdàgbà-sókè àwọn òbìnrin.

Ìjọba kò gbọdọ̀ yapa kúrò nínú irú àwọn òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àwọn obìnrin lásán bíkò ṣe pé kí wọ́n tún ṣiṣẹ́ takuntakun láti mú ìlọsíwájú bá àwọn ẹ̀tọ́ wọ̀nyí kí wọ́n sì dáàbò bò wọ́n pẹ̀lú.

Mímọ rírí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àwọn obìnrin jẹ jade gẹ́gẹ́ bí a ti rí pé, ìdá mẹ́ta nínù mẹ́rin àwọn orílẹ̀-èdè tó wà nínú Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé ni ó ti ń kópa nínú àwọn ìpàdè tó ń ri sí ìfòpin sí ẹ̀tọ́ idẹ́yẹ sí àwọn obìnrin. Síbẹ̀, àfo ńlá ló sì wà nínú kí àwọn ẹ̀tọ́ yìí wà àti kí àwọn tó ni ẹ̀tọ́ náà gbádùn irú àwọn ẹ̀tọ́ bẹ́ẹ̀, nípa pé àwọn ìjọba kò kobi ara sí mímú ìlọsíwájú bá àti dídábò bo irú àwọn ẹ̀tọ́ wọ̀nyí pẹ̀lú pẹ wọn kò dá àwọn obìnrin àti ọkùnrin bákan náà lẹ́kọ̀ọ́ tó lórí irú ẹ̀tọ́ bẹ́ẹ̀.

## ÀTẸ AKITIYAN DÁBÀÁ ÌGBÉSẸ̀ TÓ LÈ:

* Mú ìlọsíwájù bá àti dáàbò bo ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àwọn obìnrin nípa ṣíṣe àmúlò gbogbo àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, páàpáà jùlọ èyí tó dá lé ìfòpin sí gbogbo ìwà ìdẹ́yẹ sí àti rírẹ́ àwọn obìnrin jẹ.

* Ṣe àtúnyẹ̀wò àwọn òfin orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan láti ṣe àmúlò gbogbo àwọn ìpinnu ti wọn ṣe nibi ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn Àjọ Orílẹ̀-Èdè.

* Jẹ́ kí ìṣedẹ́ẹ́dé wà, kí ìyapa sì dópin nínú òfin àti ìhùwàsí àwọn ènìyàn.

* Jẹ́ kí àwọn ènìyàn nímọ̀ nípa òfin.




Àwọn obìnrin to bá wà nípò àkoso a jẹ́kí àwọn èniyàn máa fojú rere wo àwọn obìnrin yókù nipa àtẹjade ọ̀rọ̀ obìnrin ninu ìròyìn.

## ÈTÒ ÌRÒYÌN

Lásìkò yìí, ọ̀pọ̀ obìnrin ni ó ń sisẹ́ ní ilé-iṣẹ́ ìròyìn, ṣùgbọ́n díẹ̀ nínú wọn ni ó tíì de ààyè ìṣèpinnu. Ní ọ̀pọ̀ orílẹ̀-èdè ni àwọn ilé-iṣẹ́ ìròyìn kìí tíí kọrin rere ki àwọn obìnrin wọn, bẹ́ẹ̀ ni wọn kíí sìì mẹnu ba irú ìgbésí ayé àti iṣẹ́ ribiribi tí wọn ń ṣe fún àwùjọ. Ọ̀pọ̀ àwọn àwòrán àti ohun èèlò lorísìírisìi tí ó tàbùkù bá àwọn obìnrin wọn ni wọ́n máa ń gbé hàn.

Ibi gbogbo ni àwọn oníròyìn ti ní agbára ju ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ míràn lọ láti gbé ètò ìdàgbàsókè àwọn obìnrin lárugẹ. Wọ́n lè ṣe ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwon ètò tí ó máa fòpin sí gbogbo èrò kéró tí àwọn èniyàn ní nípa obìnrin. Àwọn obìnrin tún lè ṣe àfikún agbára wọn nípa nínì ìmọ̀ síi, ẹ̀kọ́ àti àǹfààní sí ètò ìmọ̀ nípa ìròyìn.

## ÀTẸ AKITIYAN DÁBÀÁ ÈTÒ TÓ LÈ:

- Ṣe àlékún ìkópa àwọn obìnrin àti ètọ́ wọn sí gbígbé èrò inú ẹni síta, àti ṣíṣe ìpinnu, pàápàá nípa àwọn ilé-iṣẹ́ ìròyìn, àti àwọn ètò ìbánisọ̀rọ̀ gbogbo tó gbòde báyìí. Ìjọba gbogbo gbọ́dọ̀ pinnu láti dí àfo tó wà láàrin ọkùnrin àti obìnrin nípa yíyàn obìnrin àti ọkùnrin bákan náà si àwọn ìgbìmọ̀ olùdámọ̀ràn, olùṣàkọ́so àti ti alábòjútó.

- Dí àwọn àlàfo tó wà, kí àyípadà sì bá bíbu ẹnu àtẹ lu àwọn obìnrin ní àwọn ilé-iṣẹ́ ìròyìn gbogbo. Àwọn ẹgbẹ́ oníròyìn, ẹgbẹ́ ìjọba, aládàání gbogbo gbọ́dọ̀ mú ìlọsíwájú bá à jọpín ojúṣe nínú ẹ̀bí, kí wọ́n sì pèsè àwọn ohun èèlò tó ṣe àfihàn orísìírisìí ipa pàtàkì ti àwọn obìnrin tó jẹ olórí ń kó;
- Ṣe àwọn ètò iṣẹ́ àti òfin ìhùwàsí nínú ilé-iṣẹ́ ìròyìn àti àwọn ẹgbẹ́ olùpolówó ọjà àti àwọn àbá míràn tí ó máa mú ìlọsíwájú bá gbígbé àwọn obìnrin jáde bí wọ́n bá ti ń làì fi funfun pe dúdú, kí àwọn obìnrin sì ní òmìnira àti sọ ohun tó bá wà lọ́kàn wọn jáde.



Awọn obìnrin loju ààńụ́, nitorinaa a gbọ́dọ̀ máa dábòbò wọ́n

## ÀYÍKÁ

Nípa ìṣàkóso àti ìmúlò àwon ohun èèlò tí Ẹlẹ́dàá dá, awon obinrin ń pèsè fún àwọn ẹbí àti aládùgbó wọn. Gẹ́gẹ́ bí olùṣe àti ẹni tí ó ń lo ọpọ àwọn nǹkan wọ̀nyí, olùtójú àwọn ẹbí àti olùkóni, àwọn obìnrin ń kó ipa pàtàkì láti múìlọsíwájú bá ìdàgbàsókè tó yè kooro. Ìdínkù tó ń dé bá àwọn ohun àlùmọ́ọ́ni tó ti wà ń, ń fa àkóbá fún ìlera, ìwàláyé àti ìgbé ayé ọ̀pọ̀ nínú àwọn ènìyàn pàápàá jùlọ àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti obìnrin gbogbo.

Síbẹ̀ àwọn obìnrin tí wọn kò fi bẹ́ẹ̀ ní ẹ̀kọ́ṣẹ́ ìṣàkóso ọpọ̀ àwọn nǹka wọ̀nyí, ni wọ̀n wá ń fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú ètò ìṣè-pinnu, tí gbogbo ìrírí àti ìmọ wọn wá di asán. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹgbẹ́ àwọn obìnrin ń gbìyànjú, síbẹ̀ ipa tí wọn ń kó nínú ètò ìjọba kò jọjú.

## ÀTẸ AKITIYAN DÁBÀÁ PÉ: KÍ WỌN:

- Jẹ́ kí àwọn obìnrin kópa pàtàkì nínú àwọn ìpinnu tó jẹ mọ́ àyíká ní gbogbo ọ̀nà. kí wọ́n di olùṣàkóso, olùgbékalẹ̀ àwọn ètò, kí wọ́n sì kópa nínú ìmúlò àti igbékalẹ̀ àwọn ètò tó jẹ mọ́ àyìká wọn.

- Fi àwọn èrò tó jẹ mọ́ obìnrin sọkùnrin sí inú àwọn òfin àti fún ìdàgbàsókè tó múná dóko.

- Ṣe àlékún tàbí àgbékalẹ̀ àwọn ètò ni orílẹ̀-èdè, àgbáyé àti Àjọ Orílẹ̀-Èdè láti ṣe àyèwò ipa tí ìdàgbàsókè àti òfin àyíká ń kó lórí àwọn obìnrin.



Ohun to dara fun omokunrin, naa lo dara fun omobinrin. Omobinrin bii omo okunrin ni eto si imo eko.

## ỌDỌ́MỌDÉBÌNRIN

Nί Ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀-èdè ni wọ́n ti ń dẹ́yẹ sí àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin láti ìgbà ìkókó. ìgbà èwe títí di àgbàlagbà. Nítorí orísìírísìí àwọn ìwà ṣẹ́ búrúkú gẹ́gẹ́ bíi dídábẹ́ fún ọmọbìnrin. yíyan ọmọkùnrin láàyò fífa ọmọbìnrin tí kò dàgbà tó fọ́kọ, ìlọ̀pọ̀ tó ń kó ìpalára bá wọn àti àwọn ìṣẹ́ míràn tó jẹ mọ ìlera àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Díẹ nínú àwọn obìnrin tí a bá wò wọ́n sí ọkùnrin ni ó ń dágbà tojú bó ni àwọn àdúgbò kan láyé yìí. Torí àì sí òfin tó ń dáàbò bo wọn, tàbí kíkùnà láti gbé irú òfin bẹ́ẹ̀ ro. Ọpọ̀ ọ̀dọ́mọbìnrin ni ojú wọn ń rí ìríkúrìí, pàpàá èyí tó jẹ mọ́ fífi ipá bá wọn lò pọ̀. Ní ọ̀pọ̀ agbègbè ni wọ́n ń dẹyẹ sí àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin lórí ẹ̀tọ́ wọn sí ẹ̀kọ́ àti ìmọ̀ ìkọ́ṣẹ́. Ó lé ní bílíọ̀nù mẹ́ẹ̀ẹ̀dọ́gún ọ̀dọ́mọbìnrin ọlọ́dún mẹ́ẹ̀ẹ́dógún sí mọ́kàndínlógún tó ń bímọ lọ́dún tí wọ́n sì ń bá ọ̀pọ̀ ìṣòro pàdé nípa ìdí èyí. Orisiirisii ìṣòro ni wọ́n tún ń kojú èyí tí àwọn ọmọkùnrin kìí sáábà kojú nípa ìlòpọ̀ pàápàá àwọn àrùn orísìírísìí bíi éèdì (HIV/AIDS).

## ATE AKITIYAN DABAA ATI:

- Fòpin sí gbogbo orísìírísìí ìdẹ́yẹ sí ọ̀dọ́mọbìnrin, ṣe àgbékalẹ̀ àti àmúlò òfin tí ó máa fún ọ̀dọ́mọbìnrin ní ẹ̀tọ́ àti dé ipò lẹ́yìn tí ará ìwájú bá fààyé sílẹ̀; ẹ̀tọ́ kan ná pẹ̀lú ọmọkùnrin láti jogún láì wò bóyá obìnrin tàbí ọkùnrin.

- Fòpin sí gbogbo ìwà àti ìṣe tí àṣà abínibí dá sile tó ń pa obìnrin lára.

- Fòpin sí dídẹ́yẹ sí àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin nínú ètò ẹ̀kọ́, ìdàgbàsókè ìmọ̀ lórí iṣẹ́ kan pàtó àti ètò ìkọ́ṣẹ́.

- Fòpin sí dídẹ́yẹ sí àwọn ọmọbìnrin nínú ètò ìlera àti oúnjẹ.

- Fòpin sí lílo àwọn ọmọ ni ìlòkulò fún ètò ọrọ̀-ajé kí wọ́n sì dáàbò bo àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin lẹ́nu iṣẹ́.

* Ṣe àlékún ipò ẹbí nípa mímú ìlọsíwájú bá ipò àwọn ọmọbìnrin.

## ẸLẸ́GBẸ́-JẸGBẸ́ ÀTI ÌLÀNÀ ÈTÒ ÌNÁWÓ

Ìwé àtẹ akitiyan ṣe àgbékalẹ̀ àwon akitiyan tó lẹ̀ mú ìyàtọ̀ wá. Bíbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ní wàràsesà àti ìjábọ̀ ṣe pàtàkì tí a bá fẹ́ kí àlá wa ṣẹ ní ọdún márùn-ún sí àsíkò yìí, ìyẹn ọdún 2,000.

Àwọn ìjọba ni ó ní iṣẹ́ tó pọ̀ jù láti ṣe láti jẹ́ kí àbá yìí di mímú lò. Síbẹ̀ naà, àseyọrí má dá lé orí àwọn ẹgbẹ́ gbogbo ní orílẹ̀-èdè, agbègbè Àjọ Orílẹ̀-Èdè, ilé-iṣẹ́ ìjọba àti ti Aládàáni, torí ó yẹ kí wọn ṣe àwọn òfin tó lagbara, tí ó máa yé àwọn èniyàn, kí wọn sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀; bẹ́ẹ̀ naà ni ó yẹ kí wọn pèsè àwọn ohun èèlò.

* Ní orílẹ̀-èdè, ìgbìmọ̀ ìṣẹlú tó ga júlọ gbọ́dọ̀ runpá runsẹ̀ síi kí àbá yìí lè di àmúlò kí ó sì ni àseyọrí. Nígbà tí ọdún 1996 bá fi máa dópin, gbogbo ìjọba gbọ́dọ̀ ti gbé àwọn ìgbésè kí wọ́n sì ṣe àwọn ètò fún akitiyan. Àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ ṣe àgbékalẹ̀ tàbí àlékún bí àwọn ìrinsẹ̀ ìjọba ṣe máa ṣiṣẹ́ sí fún ìdàgbàsókè àwọn obìnrin, kí wọn sì wá ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ọ̀pọ̀ ninu àwọn tó máa jẹ akópa tó kù.

* Ní ti àgbègbè àti ìsòngbè gbogbo, àwon àjọ tó ń rí sí ọrọ̀ àgbègbè ní abẹ́ Àjọ Ìṣọ̀kan-Àgbáyé gbọ́dọ̀ mú ìlosí-wájú bá, kí wọ́n sì ran àwọn ẹgbẹ́ lọ́wọ́ ni orílẹ̀-èdè gbogbo. Àwọn ẹgbẹ́ agbègbè náà gbọ́dọ̀ ṣe àgbéga àti ìpolongo àwọn ètò wọn fún akitiyan àti so àwọn àbá yìí di àmúlò láàrin àwọn àsìkò tí a là kalẹ̀ àti àwọn ohun èèlò tó wà.

* Ní ti àjọ orílẹ̀-èdè, gbogbo amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Àjọ-Ìṣọ̀kan Àgbáyé pata ni ó gbọ́dọ̀ ní àwọn ohun èèlò tó yẹ, pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ tó kún láti ṣe àyẹ̀wò àwọn akitiyan tí àwọn orílẹ̀-èdè àti agbègbè gbogbo ti se. Àwọn àjọ olówó káàkiri àgbáyé ni a rọ̀ kí wọ́n ṣe àtúnyẹ̀wò àwọn òfin wọn láti rí i pé àwọn ètò ìdálókòwò wọn ṣe àwọn obìnrin ní ànfààní.

Láti jẹ kí àwọn àbá yìí di àmúlò, kí ìmọ̀ràn sì wà lórí ọ̀rọ̀ ọkùnrin sóbìnrin, ìpè tún ti lọ sí ọ̀dọ̀ akọ̀wé àgbà Àjọ-Ìsọ̀ka Àgbáyé láti ṣe àgbékalẹ̀ ipò kan tó ga ní ọ́ọ́físì rẹ̀. Wọ́n tún pe ìpè fún àwọn tó bá ní, láti pèsè owó tó tó pẹ̀lú àwọn ohun èèlò míràn káàkiri àgbáyé.

*Produced by:* **The United Nations Development Fund for Women (UNIFEM)**
**And The United Nations Information Centre, Nigeria (UNIC)** Tel: 2694886
*Printed by:* **Sup-Del Prints & Company Limited** Tel: 824807, 823871